# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No 867 WEDNESDAY DECEMBER 9, 1964 [2D]

## Ejo Igbese Egbefa Ponun Ti Nwon Pe Akintola Di Odun To Mbo

EKO:- Ni ojo Isegun ti iṣe ọjọ kẹjo osu yi ni irohin fi ye wa pe ẹjọ igbese owo ile ti ile iṣẹ ti nkole eyi ti a npe ni B. Stablim and Company pe Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye S, L. Akintọla yio bẹrẹ ni ọjọ kẹrindilọgbọn ati ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu kini ọdun to mbọ yi lori owo ile ti ile iṣẹ na kọ fun Oloye S. L. Akintọla ni ilu rẹ Ogbomọṣhọ eyi ti iye owo na jẹ (£12,397 3s. 1d).

Ile isẹ ti nkọ ile na nfẹ gba iye owo ti ile iṣẹ na kọ fun Oloye Akntọla eyiti owo na ku (£10, 397 3s 1d) Ninu owo ti awọn ile isẹ ti nkọ ile na fẹ gba gẹgẹbi owo itanran ni nwọn tun pe ẹgbẹwa pọn un (£2,000) lori pe Oloye Akintọla kuna lati tete san owo to jẹ ile isẹ na.

Ninu ẹrọ ti Agbẹjọro fun awọn ile isẹ ti nkọ ile na Ọgbẹni B. A. Ajibọla fi ye Adajọ ile ẹjọ na pe on fẹ ki ile ẹjọ na tete fi asiko ti ko ni pẹ pupọ si igbati nwọn yio gbe ẹjọ na dide lati gbọ nitori pe ile isẹ to nkọ ile na si wa ninu isoro pupọ lati san owo oṣu fun awọn oṣisẹ toba wọn nsisẹ bayi.

# AZIKIWE TU ILE IGBIMỌ AṢOFIN APAPỌ IJỌBA KA!

## AWỌN ENIA ILẸ NAIJIRIA YIO DIBO NI IPARI OṢU YI

**EK :- Asẹhinwa asẹhinbo asiko ti awọn enia ilẹ Naijiria nreti rẹ ti de tan bayi eyi to fi jẹ pe lati nkan bi oṣu diẹ s'ẹhin ni gbogbo olube ilẹ Naijiria ti fi oju sọna pe nigba wo ni ireti wọn yio si de lori eto idibo titun si ile igbimọ aṣofin ti apapọ ijọba ilẹ Naijiria lati yan awọn ẹgbẹ Oṣelu titun ti yio ṣe akoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria fun ọdun marun miran.**

Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ilẹ Naijiria ni Olutu tabi Igbona ara ti nmu lori eto idibo titun miran lati nkan bi oṣu diẹ sẹhin eyi to jẹ eto ẹyẹ ipade ipolowo ibo si ti nlọ kakiri orilẹ Naijiria lati le fi ma to awọn enia ilẹ Naijiria leti ohun pataki ti ẹgbẹ Olukuluku yio ṣe fun eto idagbasoke ilẹ Naijiria lẹhin idibo to mbọ yi. Ọpọ lọpọ awọn ẹlomiran lo si jẹ pe nwọn si ti fi f'oju le ọna fun ọjọ kanna ti A l a k o s o ilẹ Nai— jiria yio ro ninu ara rẹ eyi Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria yio tun fi ọwọ silla ti tu ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria na ka.

Nigati o di deede agogo mejila oru ọjọ Aje ti ise ọjọ keje osu yi ni asiko awọn ọmọ ilọ igbimọ aṣofin ti



Alhaji Abnbakar Taf wa Balewa



Dokita Nnamidi Azikiwe

papọ Ijọba ilẹ Naijiria pari eyi to je pe ninu ọjọ kejila ọdun 1959 ni awọn enia ilẹ Naijiria fi ibo yan wọn si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria na.

Nigbati o di deede agogo mejọ abọ owurọ ọjọ Isẹgun ti ise ọjọ kẹjọ osu yi ni irohin de ọwọ wa lati ile Alakoso ile Naijiria ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe pe ako ko awọn omọn ile igbimọ aṣofin ti Ijọba apapọ ilẹ Naijiria to ni ale ọjọ Aje ti iṣe ọjọ keje osu yi ati pe ni agbara ti Ijọba ile Naijiria fi le on lowo pe on tu ile



Oloye Festus Okotie—Ebor

igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba na kan ni ọjọ Isegun iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi lati ṣe idibo titun miran ki awọn Olugbe ilẹ Naijiria yan egbẹ oṣelu miran eyi ti nwọn ba mọ pe yio se akoso wọn lori ọna ti yio fi tọ ati eyi to yẹ lati ṣe eto ti yio mu ilọsiwaju ba awọn Olugbe ilẹ Naijiria.

Ṣugbon gẹgẹbi eto ofin ti ile Naijiria. awọn ẹgbẹ oṣelu ni lati fi ọjọ mọkanlelogun ṣe eto eyẹ i p a d e ipolowo ibo kakiri ilẹ Naijiria fun awọn omọ ẹgbẹ wọn ati pe ki Olukuluku ma ṣe alaye ohun ti ẹgbẹ wọn yio ṣe ti nwọn ba ti bori ibo to mbọ yi.

Ṣugbọn ni ọjọ ọjọ'Ru ti i ṣ e ọ g b ọ n j ọ o ṣ u yi ni awọn enia ilẹ Naijiria ni etọ lati lọ dibo ki nwọn yan awọn ẹgbẹ oṣelu ti yio ṣe akoso wọn lẹhin ti nwọn ba dibo. Gbogbo a w ọ n ẹgbẹ oṣelu bayi ni o ti mura kikankikan bayi fun eto ipolowo ibo lati le ṣe ọna gegebi nwọn y i o ṣe gba akoso Ijọba apapọ ti nwọn yio ṣe idibo rẹ bayi.

IWE OJU EWE KẸFA

# KI YIO SI IJOKO DẸMỌ KAN NI ILE-IFẸ

## Lati Ọwọ ỌMỌ – ADIMULA



Dọkita M. I. Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

YORUBA NI:- Aki iba onile jẹ ki a ba onile mu ki o di ọjọ iku rẹ ki a yẹra (Ewo-Orisa). Bi idamu ati wahala ti ẹgbẹ Dọmọnu nfi oju ọmọ Ile Ifẹ ri pọ ju eyi lọ ki yio si ijoko ẹgbẹ Dọmọnu kan ni igboro Ile-Ife lailai bikoṣe ti UPGA. Ohun ti koni jẹki a ri ijoko ẹgbẹ Dọmọnu ni Ile Ifẹ ni wipe, lati ọjọ ti alaiye ti daiye awọn baba wa ko pa ni itan fun wa ri wipe awọn ti di ẹru Hausa ri, ohun ti a ngbọ lẹnu wọn lati igba iwa ṣẹ ni wipe;- Bi o kanran ki a dọbalẹ fun gambari, ki a kuku rọju ku ati wipe Olori ni Ile Ifẹ jẹ larin gbogbo ilẹ Kuarọ o jire? A si mbẹ Olodumare na wipe Ki o mase sọ wa di ero ẹhin lailai.

E o ma gbọ wipe ti ẹgbẹ Dọmọnu n Ifẹ nse eni to ba nsọ bẹ ki paro nito ripe ọmọ Ile Ifẹ jẹ eda kan to beru wahala tabi. ki a sọ wọn di ẹlẹwọn ati wipe nwọn ti ri i wipe Oniyangi ni ẹgbẹ Dọmọnu nwọn ko si fẹ ki nwọn fi yangi wọn fọ Ata epo ti nwọn gbe kalẹ eyi je ohun pataki ti o mu OloyeRẹn.ilẹkun Fani mọkun Kayọde di Balogun apapandọdo si ile Ifẹ ki wọn o le gba wipe ti ẹgbẹ Dọmọru ni awọn nse.

OLOYE ỌRUNTỌ

Otitọ ọrọ to fara pamọ ninu iwa ti ọmọ Ile Ifẹ nhu pẹlu ẹgbẹ Dọmọnu ni wipe ki Oloye Kayọde ki o kuro ni Balogun ki o pada di Oloye Ọruntọ ti ise igbakeji ỌNI Ile Ifẹ ọmọ Ifẹ ko ni fi ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ Iranwọ Odua pẹlu Ọmọ Omisade Ogbolu ti ise ọmọ bibi inu wọn to mbẹ lọgba ẹwọn silẹ.

# YẸYẸNATU

## ONIYẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:- Olotu, njẹ ẹ gbọ wipe Salamọ tu pẹlu ọkọ rẹ ja?

Olotu:- Ṣe ni Abẹokuta

Yẹyẹnatu:- Hen o.

Olotu:- Ki lo fa a?

Yẹyẹnatu:- Ẹnyin ko gbọ ni? Ṣebi ẹni aburo yin ni Salamọtu?

Olotu:- Nko gbọ Boya o wa sile ko ba mi.

Yẹyẹnatu:- Nigbati ọkọ rẹ de lati ibi iṣẹ ko ba onjẹ lo ba bẹrẹ ija.

Olotu:- Ha, ara ohun ti mo nsọ fun Salamọtu ni yẹn.

Yẹyẹnatu:- Salamọtu, ni ejọ ori kọ

Olotu:- Ẹjọ tani?

Yẹyẹnatu :- Oni ejọ ẹgbẹ Ọlọwọ ti o sofin pe enikan ko gbọdọ ta ọja ni Abẹokuta ni

Olotu:- Ẹgbẹ N N D P kẹ Irọ. Nitori kini nwọn ṣe le sọ be kẹ? Irọ

Yẹyẹnatu:- Nwọn ni nitoripe Akintọla A r e Ọnakakanfo mbọ ni

Olotu:- Irọ. Nitori Akintọla ko le gba ki nwọn febi pa enia

Yẹyẹnatu:- Nko ni o gba ṣugbọn awọn ẹmẹwa rẹ ni o sofin

Olotu:- Isọkusọ ti nwọn nsọ ni yẹn

Yẹyẹnatu:- Kini ẹ nsọ Ohun to nṣẹlẹ ni Ibadan na nkọ ṣe irọ ni?

Olotu: Emi ko mọ.

Yẹyẹnatu: Njẹ ẹ mọ ohun to ṣẹlẹ ni Campos ni ijeelo·

Olotu: Kini?

Yẹyẹnatu:- Ti awọn Ọlọwọ nja Ọbẹ.

Olotu: Ṣe o tan?

Yẹyẹnatu: Njẹ ẹ mọ ohun to ṣẹlẹ ni Ibadan paa pa ni ijeelo?

Olotu: Kini?

Yẹyẹnatu: Ti awọn ọmọ ile iwe kekeke ti ibi ipade Akintọla de hosipital

Olotu: Ṣe o tan?

Yẹyẹnatu: Ṣe o tan, ṣe o tan, ṣe ohun rere ni gbogbo eyi ni?

Olotu: Nitori Alajọbi ni

Yẹyẹnatu: Tani Alajọbi?

Olotu: Akintọla ti sọ pe Ẹgbẹ Alajọbi l'ẹgbẹ Ọlọwọ.

Yẹyẹnatu: Awọn wo ni nwọn jọ bi? pẹlu Akintọla

Olotu: Bere lọwọ rẹ

Yẹyẹnatu: Awọn ẹgbẹ rẹ kẹ?

Olotu: Ọmọ ha le buru ki afi fun ẹkun pa

Yẹyẹnatu :- Ṣe bi Akintọla ṣe nwi ni yẹn?

Olotu: Otitọ ha kọ? Akintọla ha le buru kiẹ gbe e fun ẹkun pa jẹ?

Yẹyẹnatu: Ṣebi omi ti enia ba da siwaju ni o yẹ ki o tẹ ṣe Akintọla ni nitori Awolọwọ buru lo se dero ẹwọn Hẹn bi a ba gbe on na fẹkun pa, oro to da ero iwaju ni awa na da a.

Olotu:- O ti sọ pe bi awọn ba wọle Ibo awọn ọba yio da Awolọwọ silẹ

Yẹyẹnatu:- Akintọla sọ bẹẹ?

Olotu:- Bẹẹ ni.

Yẹyẹnatu:- Kini ṣe ti ko sọ fun awọn ẹgbọn rẹ ni ilẹ Hausa ki nwọn fi Awolọwọ silẹ nisisiyi bo ṣe otitọ ni o nwi

Olotu:- Emi ko mọ.

Yẹyẹnatu:- Ohun to wa nibẹ ni pe enia gbọdọ ṣọra lọdọ ẹniti ẹnu rẹ ba dun

Olotu:- Ko buru ṣugbọn ṣọra rẹ mo nwi fun ọ.

Yẹyẹnatu:- Ẹ ṣe o ṣugbọn yio ya yin lẹnu nigbati NNDP ba sọ mi di enia nla.

Olotu:- Nitori kini.

Yẹyẹnatu:- Ẹnyin ẹ ma a wo o ṣe awọn gọ ni; ọwọ mi ni nwọn ri Mo ti ni ki nwọn mu owo wa

Olotu:- Bẹ ẹ wa a gba a.

Yẹyẹnatu:- Yes kẹ mo nlọ

O dabọ



Oloye S. L. Akintọla
Olori ẹgbẹ Dẹmọ

Bi ojulowo ọmọ Ile Ifẹ kan ba nsọ wipe, ti ẹgbẹ Ọlọwọ ,tabi, ti Dẹmọ ni on nṣe,o sọ kole ilu gbe ni, ki ṣe pe o nsọ pẹlu ẹdun ọkan rẹ. Ki aṣiri ohun ti mo sọ ii o to tu sita, o dẹhin ti a ba dibo to mbọ yi nigbana ni yio to han si ẹnikẹni wipe kosi ojulowo ọmọ Ile Ifẹ kan ti o nse ti Oloye R. F. Kayọde ati Dọmọnu ẹgbẹ rẹ ati pe nigbana ni ọmọ Ifẹ yio to fi han wipe Iran Oduduwa kan kooni se ẹru Husa lailai.

# YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan. 22 – Feb 20:–) Bi iwọ yio ba ṣe orẹ, jẹki o jẹ enia pataki ni iwọ yio ṣe ore fun, bi bẹkọ, ẹbi ni iwọ yio gba lori rẹ; idina yio wa fun ọ lọdọ obirin ti iwọ mbe binu ti iwọ yio si ma jowu.

PISCES (Feb. 21 – Mar. 20:–) Arẹ mu ọ, ara rẹ ko ya saga, ṣugbọn maṣe fi eyini kẹwọ lati ma ṣe ọle, maṣe fi iṣẹ ti o ni lati ṣe silẹ, ma si ṣe gbagbe awọn ọrẹ rẹ, nkan yio ru ọ lẹju pupọ.

ARIES (Mar. 21 - April 20 ; ) O dabi ẹni pe ohun gbogbo rorun lati ṣe loni, adele ba rere, arinna ko rere ni fun ọ loni, iwọ yio gbero lati lọ si ajo tabi ki alejo kan wa wo ọ.

TAURUS (April 21 - May 20) Ire yio bọ joko loni ara rẹ yio si ya, ori rẹ yio si pe, itẹlọrun yio wa fun ọ nibi gbogbo.

GEMINI (May 21 – June 21) Ki o kapa afojudi rẹ ati inu burukụ ti o ni, bi bẹkọ, iwọ ri idiwọ ninu iṣẹ rẹ maṣe ba ẹnikan gbonu, iwọ yio si ma gbayi larin ẹgbẹ ati ọgba.

CANCER (June 22 – July 22) Ṣe ohun kan ti o wu ọ, ki inu rẹ le dun ki ara rẹ si ya si gbogbo enia, iṣẹ nlọ fun, irohin ayọ mbọ wa ba ọ.

LEO (July 23 - Aug. 23) Maṣe jẹ ajẹrẹge, ki o ba le ni alafia ati ara lile ṣọ ahan rẹ nigbati oba nsọro, iwo yio gbayi lodo iyawo rẹ ati lẹnu iṣẹ.

VIRGO (Aug. 24 – Sept. 23) Iwo ko nile mọ ohun ti o nṣe ẹ tan, yala olala ni tabi oju aiye lo wa, sibẹ ninu palaba ninu ṣegede ẹrẹkẹ yio ṣekan gba awọn ọrẹ rẹ gbọ, ki o si tẹle imoran ti wọn ba fun ọ.

LIBRA (Sept. 24 - Oct 23) Bi o ba ba awọn alagidi enia rin papọ loni iwọ ko ni le gbadun ni akoko owurọ yi, ṣugbọn gbajumọ yio gbe ibiti o ba bajẹ.

SCORPIO (Oct 24 - Dec 22) Lakoko ti o ba mbẹ lẹnu iṣẹ, ma a lo ẹsẹ gigun ati gbajumọ lati fi wa ilọsiwaju iṣẹ rẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ire ṣẹjọ fun ọ lo ni iwọ le ba iyawo rẹ gbero pe kio baọ kalọ si irin ajo ire ni irin ajo na yio jẹ fun iyawo na ati itẹlọrun ninu iṣẹ rẹ gbogbo larin awọn gbajumọ ẹgbẹ rẹ

CAPRICORN (Dec 22–Jan 21) Ọjọ oni dara fun awọn ti o nya ere tabi aworan ohun gbogbo ti oba dawọ le loni ire ni yio jasi

## Imoran Fun Awon Ọmo Ile - Ẹko

Lati Ọwọ Ọlatunde Adesanya

Ẹnyin ẹlẹgbẹ mi akoko fẹrẹ to bayi lati mọ pe ọdun nyi lo si opin mo si lero pe ti o ba ku ọsẹ diẹ si a o si gba isimi fun ọdun keresimesi eyi ti gbogbo wa si lero pe ninu isimi ti a o gba yi a ni lati gbọ esi iṣẹ ti a ti nṣe ninu ibẹrẹ ọdun yi lati ọwọ awọn Olukọ wa.

Ṣugbọn ẹnyin ẹlẹgbe mi ọpọlọpọ ni yio ma yọ ti ọpọlọpọ yio si ma sọkun kikoro nigbati ko ti ṣe dada ninu ẹkọ rẹ eyi to fi jẹ pe awọn ẹlẹgbẹ rẹ miran yio si bọ sinu iwe titun eyi to si jẹ pe eyi to ka ninu ọdun yi ni yio ka lọdun to mbọ.

Nitori eyi ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ẹ ma ṣe fi owurọ ṣere nitori iṣẹ logun iṣẹ ti ẹ ba ri enia kan to ba nlo mọto loni ki iṣe pe oju rẹ ko ti ri nkan to ti pọ s'ẹhin ṣugbọn ifi ara da lo mu ki enia ni ilọsiwaju. Nisiyi mo ro pe ọdun si ti ọ lọ si opin gegẹbi a a ọṣe gba isimi wa yi ki a ma ṣe fi ṣe ere nikan ti ko ṣe pe ki a mura ki a si ma ka iwe ti un ti a ma bẹrẹ si ni ka ninu ọdun to mbọ yi.

Ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ti ko ṣe dada ninu ọdun yi mo ro pe to ba di ọdun to mbọ e o si mura lati le yege ninu ẹkọ nyin ki ẹ le ni ilọsiwaju ninu ọdun to mbọ eleyi yio si jẹ ohun iwuri fun emi dajudaju pe ko si gẹgẹbi o le ṣe ri mo ni lati pass ẹkọ mi nitori lati igba ti mo ti wa ni ile ẹkọ ni mo ti ngbiyanju lati le ma ni ilọsiwaju ninu ẹkọ mi ati pe mo rọ ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ki a mura ki a le di bi awọn ọjọgbọn to mọ iwe de gongo or awọn bi oyenu, Aluko Chike Obi, Tai Ṣolarin, Odumosu, Baba wa Azikiwe, Baba wa Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn miran ti aye ko gba lati darukọ wọn ninu iwe ẹ yin ẹlẹgbẹ mi ẹ di igba dẹ mo si fẹ ki olukuluku lọ mu ọrọ mi yi si ọkan dada.


# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



Aworan ẹgbẹ yi fihan gban gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wọ ni ara rẹ ti nyọọ lẹnu nigbagbogbo ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba ṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si soro pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

CYCLOVEN

Ọpọlọpọ egbogi ni o wa ti a nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ma a npolowo nwọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya ni a le ri mẹwa ninu awọn ọun ti o leṣe iwosan arun ty daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn gbe lọ si ile iwosan lati lọ ge eyiti o ba nyọ jade omusu ku nipa be awọn o bọ lọwọ rẹ patpaata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bere bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwu eran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ sode ninu ori uṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ walẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ti a tanigboro Naijiria bere ni :

NIGERIA MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos
WATER-LOO MEDICINE STORE
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Oja
ATI NI ṢỌBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN.



# KERE O! Akiyesi Pataki

## Antoin Tablets ! Antoin Tablets !!

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin, Mo ba yin yọ Ẹ ku afojuba egbogi pataki ti a ṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Oniṣẹgun (Specialist) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:—

IGBỌNA:- Eyi jẹ Arun ti o ṣọpọ nisisiyi papa julọ arun awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ TULU LUKULUKU OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO Jọwọ danwo ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko to afojuba Bere iwe ti ẹ o fi lowọ ẹniti o ba nta Egbogi na fun nyin: O daju han u . Ẹ o ri ṣe re lẹhi iṣeju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ Oniṣẹgun adugbo rẹ.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone;- 23745.
LAGSO

# Irinajo Mi Si Agbo'Ile Ifẹlodun

Mo ki gbogbo ẹnyin onkae Irohin Imọlẹ ẹ nbe nbẹhun e si ku ipalẹmọ ọdun keresimesi mo si tun ki ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina ẹ ku ipalẹmọ idibo apapọ Ijọba ti o nbọ yi o. Loni ki o ma se ya yin lẹnu pe mo fi ẹnu ba ọrọ ibo ṣugbọn loni ki iṣe ọrọ idibo ni mo fẹ sọ mo kan fi iyẹn ran yin leti ki ẹ mura silẹ.



## Oloye Fillip Gbenle

Gẹgẹbi mo ti se ileri fun yin ni ijẹta pe ti o bu diẹ lo ni ngo sọrọ lori iwe ti Bale Ijọmu Oro kọ si Oloye Phillip Afọlayan Gbenle lati fi han araiye pe nwọn ti gba tọwọ tẹsẹ gẹgẹbi ọkan ninu awọn Oloye rẹ nilu Ijọmu Oro.

Ṣugbọn kini to bẹrẹ ọrọ mi na ngo tun mẹnu ba ọrọ diẹ lori inawo ti Eko, nitori nko ti sọ irohin na tan lori inawo ti o ṣẹlẹ ni No 25 Iṣaga Rd. ni ọjọ iwuye yi.

Ni ijẹta mo ya bara lati sọ diẹ fun nyin nipa whala ati inawo ti Ọgbẹni wa gba jumọ oniṣowo atata ilu Eko ti iṣe Ọga agba fun ile iṣẹ ti o nta ogun nilu Eko ti a npe ni A K. Karimu Anjola & Bros ni ita Balo gun, Ọgbẹni A K Karimu Olabamiji Gbenle ti iṣe aburo Oloye Gbenle na ni ọjọ iwuye re

Nigbati o di irọlẹ ọjọ wuye b. gbogbo alabaṣeyẹ iti pelu pese silẹ onilu atata Ejirẹ Igbaja si ti de ti yio bẹrẹ ni ọjọ na, lẹhin ti oloye ti fi oiṣiriṣi onjẹ tẹ wọn lọrun tan ni awọn sarakisakaki ati awọn b i Amofin, Adajọ ti pe ṣamuṣamu si arin agbo yi

Nigbati mo nwo iwaju onikaluku wọn mo ri awọn ọti olowo iyebiye gẹgẹbi Sinapu, Gini, ọti ẹlesin funfun (White horse) ma teli ati oriṣiriṣi bia.

Pẹlu awọn, ẹja ati edlẹ ti a tun din pẹlu ororo eyiti nwọn yio ma fi gbe awọn ọti nabi ọwun.

Nigbati o si ma fi to dee de agogo meje agbọ ijọ na ti kunsọsọ ti ejirẹ igbaja paapa si wa bere si fi orin aladun pẹlu ohun iyọ rẹ da gbogbo awọn e ia pataki rẹ da wọn laraya.

Bi gbogbo rẹ si ti nduu yungba ni to nri awọn loya ati gbajumọ Eko ti nwọn mbọ si agbọ pelu awọn ọmọ jaiye jaiye obinrin ti nwọn si nfi ẹse rajo pelu Oloye.

Nwọn si jo ijo ayọ yi mọ; ju ọjọ keji percgeede, T. O fi je pe ko si eniti o wa ni adugbo yi ti o sun mọju ti gbogbo won si ti ilekun ile won lati wa si agbo ijo na nitori orin Ejire nitori Igbaja dun o si ma nfani mora ni Phillip Gbenle ṣe bebe ni ọjo na Diẹ ninu awon enia pataki ti Oloye wa fiiwe pesibi iwuye re na nwọn si na wabi wosi owo ni ọjọ naniyi lọya L.J.Dosumu, lọya Ajayi Akanni, babira oniso..o Yesufu Aa ni onisowo pataki lati Ghania, Karimu Bandele Ogundiran Afẹnifẹre, petter Ogu bayọ, Paul Olori Geonge biyẹmi, Rufus Ajikobi, Je Alaga, Awodele Elemesho Ọgbẹni S. L Oni L. A Atun de, Oyeyi Ogunjobi Baba ẹgbẹ Oto, P. Oladimeji K. Adeoti S. T Odunga L. Adewale Ọgbẹni Latifu Balọla J. Aranta, E. Ọmọle A A. J. Ọbamọgun, M. Oni,

Ki nto pari ọrọ mi oni mo fi iwe mi yi ki ọgbẹni wa lọya wa L J. Dosumu ati gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na pe uwọn ku inawo ọjọ o ire a kari gbogbo wo o luwa yio si ma bo aṣiri o ikaluku wa o.



Aworan yi ni ti igbati Oloye Phillip Afọlayan Ajiboye Gbenle nfi ẹsẹ rajo pẹlu awon alabaseye ojo na, onki owo bọ apo la'i yo Korensi fun onilu ọjọ na Diẹdiẹ ni Ọlọla njo, Olowo ki njo bahun ẹ sa ma milẹngbe bi ti Eko.

Ẹ ku Ijo, Oloye oye a mọ ori o.


## Aiye Toto Afrcan Healng Home

Bi ogun itaia Ti o daju Ti a ṣe ni Turari pẹlu ndera. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko tc afojuba oriṣiriṣi aruu ati ilọsiwaju

lẹnu iṣẹ pẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ wa

Office
7, Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin

## Ipolowo Ọja Rẹ Ko Tį Yege

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU
IROHIN IMỌLE
T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVRTISMENT MANAGER

IROHIN IMỌLE
16, Bamgbose Street Phone 21985

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO 867 WEDNESDAY DECEMBER 9, 1964 (2D)


## Ọmọ 'Kunrin Kan Ku Ninu Jamba Mọto

IKẸRẸ-EKITI:- Jinijini da bo gbogbo enia nigbati irohin kan gbogbo awọn enia ilu Ikẹrẹ-Ekiti pe ọmọ kunrin kan to nkọ iṣẹ Dirẹba eyi ti irohin fi ye pe ọmọ kunrin na ti orukọ rẹ njẹ Kẹhinde jabọ lati inu mọto akero kan nigbati moto na ngbinyanju lati gun oke kan lọna Akurẹ si Ondo eyi ti moto na tẹ' pa lẹsẹkẹsẹ ti o jabọ ninu moto na

Irohin lati ọwọ awọn Ọlọpa fi ye wa pe gẹgẹbi mọto na ti ngbinyanju lati gun oke na ti ko le gun oke na eyi to fi jẹ pe ọmọ iṣe mọto na Kẹhinde si fẹ gbinyanju lati fi igi nla kan si ẹhin taya mọto na eyi to jẹ pe o yẹ lẹsẹkẹsẹ ti o fi jẹ pe ọmọ kunrin na si ṣubu ti mọto na si fi tẹ ẹ pa lojiji eyi to fi jẹ pe Dirẹba moto na ko si mọ rara.

Irohin lati ọwọ awọn Ọlọpa na tun fi ye wa pe nwọn ti gbe Oku ọmọ kunrin na lọ si ile iwosan ti lukuluku ti ilu Akurẹ fun ayẹwo. Ṣugbọn awọn Ọlọpa si ti mu Dirẹba mọto na bayi lati lọ bere ohun to ja iṣẹlẹ jamba mọto to pa ọmọ iṣẹ rẹ bayi.

# Azikiwe Tu Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Ka !

## Lati Oju Ewe Kini

Gbogbo ijoko ti awọn enia ilẹ Naijiria ti nwọn yio ti yan awọn enia ti yio ṣe Aṣoju wọn ni ile igbimọ aṣofin titun na jẹ ọdunrun o le mejila (312 Seat ) eyi to jẹ pe ni ipinlẹ Ariwa Ijoko to nwọn yio dibo si lati yan awọn Aṣoju lọ si ilẹ igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria na jẹ mẹtadinniadọsan (167 Seats) ipinlẹ Ila Orun Naijiria jẹ ọgọrin (70 Seats) ipinle Iwọ Orun jẹ mẹtadinlọgọta [57 Seats} ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria jẹ mẹrinla (14 Seats) ati ilu Eko eyi to jẹ ijoko mẹrin (4 Seats).

Awọn ẹgbẹ oṣelu to jẹ pe nwọn ti nmura lori ijoko na lati ja ijakadi gẹgẹbi nwọn yio ṣe bori ibo na ni ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA eyi ti ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ẹgbẹ Afẹnifẹre (A. G ) ati ẹgbe ilọsiwaju ipinlẹ Ariwa NPF jijọ papọ lati gba akoso Ijọba awọn ẹgbẹ ti nwọn yio ba ẹgbẹ N. N. A. eyi ti ẹgbẹ Olomi (NPC) ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ẹgbẹ MDF. ẹgbẹ



Alhaji Ribadu



Ọgbeni Aja Wachukwu

NDC ati ẹgbẹ Dynamic Party jijọ papọ.

lati ṣe ọna gẹgẹbi nwọn yio ṣe gba akoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria titun na.

Lasiko idibo ti ọdun 1959 eyi ti nwọn ṣe idibo rẹ ni ojọ kejila oṣu kejila ọdun 1959 eyi to jẹ pe ko si ẹgbẹ kankan ninu awọn ẹgbẹ to jẹ pataki to nṣe akoso Ijọba ni ipinlẹ mẹta to wa ni ilẹ Naijiria lasiko na eyi ti iṣe ẹgbẹ Olomi NPC ti nṣe akoso Ijọba ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria, ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti nṣe akoso Ijọba ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nse akoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lasiko na.

Lẹhin abayọri idibo ti ọdun 1959 ti ko si ẹgbẹ kankan to ni agbara lati ṣe akoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria nigbana ni egbe Olomi (N P C ) ati egbe Alakukọ N C N C si jijọ papọ lati ṣe akoso Ijọba ile Naijiria lasiko na, eyi to jẹ egbe Afenifere lo si jẹ ẹgbe to nṣe Alatako si Ijọba ti ẹgbe Alakukọ ati Olomi jijọ papọ ṣe nigbana.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti o ti fi igba kan wa gẹgẹbi Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Naijiria lasiko na o si lọ si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria eyi ti o jẹ alatako rẹ ni alẹ ojọ keje oṣu yi gẹgẹbi olori Alatako si apapọ Ijọba ilẹ Naijiria.

Nigbati Oloye Awolọwọ fi ipo rẹ silẹ ni ipinlẹ Iwọ Orun lo si fi gbakeji olori ẹgbẹ rẹ gẹgẹbi Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun titi ija ko fi bẹ silẹ larin egbẹ na ninu oṣu karun ọdun 1962 eyi ti Oloye S. L. Akintọla fi lọ da ẹgbẹ tirẹ silẹ eyi ti a npe ni



Ọgbeni R A Njoku

UPP nigbana ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria fi gbe ofin pajawiri si ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyi ti Oloye Dọkita M. A. Majẹkodunmi fi wa gẹgebi Alakoso Ijọba ipinlẹ na.

Lẹhin eto ofin pajawiri ni ẹgbẹ UPP jijọ papọ ti nwọn gba akoso Ijọba lọwọ ẹgbẹ Afẹnifẹre titi



Dọkita Majẹkodunmi

ẹgbẹ na ko fi tuka ti nwọn sọ di ẹgbẹ NNDP.

Eleyi lo si mu ki ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre jijọ wa papọ lati ṣe eto gẹgebi nwọn yio ṣe gba akoso apapọ Ijọba ile Naijiria bayi.

Eleyi ni yio je igba ekini ti egbe Demọ NNDP yio lọ fi ara han awọn enia ile Naijiria gegebi egbe kan ti yio gbe apoti ibo sile ninu eto idibo eyi ti yio jẹ ti idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria ti yio je igba kini. Ti idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria na ba ti waiye ni ọgbọnjọ oṣu yi o se iṣe ki a gbọ abayori eto gbogbo ijoko ibo na fun orilẹ ede Naijiria ni ipari oṣu yi eyi ti iṣe ọjo kọkanlelọgbọn oṣu ti a wa yi eyi ti iṣe ọjọ aisun ọdun titun ti 1965.


Printed And Published by Modupẹ Printing Press. 16 Bamgboṣe Street Lagos Phone 21985
Acting Editor: (Adele Olotu) 'BAYỌ TIAMIYU 26, Omididun Street Lagos (9/12/64)